“Ìṣesi ti ẹrú maa n sunmọ Oluwa rẹ ju nibẹ ni ìgbà ti o ba wa ni iforikanlẹ, ki ẹ yaa maa ṣe adua ni ọpọ̀lọpọ̀”

Láti ọdọ̀ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- pe ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Ìṣesi ti ẹrú maa n sunmọ Oluwa rẹ ju nibẹ ni ìgbà ti o ba wa ni iforikanlẹ, ki ẹ yaa maa ṣe adua ni ọpọ̀lọpọ̀”.

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣàlàyé pe ìṣesi ti ẹrú maa n sunmọ Oluwa rẹ ju nibẹ ni ìgbà ti o ba wa ni iforikanlẹ; ìyẹn ni pe ẹni ti n kirun maa fi ibi ti o ga ju ti o si niyi ju ninu ara rẹ lé ilẹ ni ti ìtẹríba ati irẹlẹ fun Ọlọhun ti O lágbára ti O gbọnngbọn, ti o si wa ni iforikanlẹ. Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti wa pàṣẹ ṣíṣe adua ni ọpọ̀lọpọ̀ ni iforikanlẹ, o maa wa kójọ ninu ìyẹn irẹlẹ fun Ọlọhun pẹlu ọ̀rọ̀ ati ìṣe.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/5382